# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 1566 SATURDAY, MARCH 28, 1964 (2D)

## Ijọba Le Ẹgbaa Awọn Ibo Kuro Ni Ipinlẹ Ariwa

KANO:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi ni awọn alaṣẹ Ijọba Ipinlẹ Ariwa bẹrẹsi pin iwe fun gbogbo awọn ọmọ Ibo ti nwọn wa ni Ipinlẹ Ariwa ti nwọn jẹ onisọwo pe ki nwọn tete ma a palẹ gbogbo awọn ohun ini wọn mọ kia-kia ki nwọn si jade kuro ninu arin igboro ilu Kano.

Alaga Ijọba Ibilẹ Kano Alhaji Maa Abdulai ṣe alaye fun awọn oniwe irohin wipe on fi ọwọ si iwe na, nitootọ ni Ijọba le awọn enia Ipinlẹ Ila-Orun (Ibo) kuro ninu ilu ati wipe nwọn ko tun gbọdọ ma a wa ta ọja ninu ọja ilu Kano mọ nitoripe ọja na ti nkun ju, inira ni o si njẹ fun awọn mọto lati ma a kọja nitori ọpọ enia.

Nigbati awọn enia na (Ibo) ri iwe na gba, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti ranṣẹ lọ si ọdọ Alhaji Ahmadu Bello ti iṣe Alakoso Ijọba lati ba wọn yẹ ọrọ na wo ṣugbọn a gbọ ni irọlẹ ana wipe ẹgbaa enia (2,000) ni Ijọba ti le kuro ni Ipinlẹ na. Awọn enia na ti nfi ilẹ ti nwọn kọ ni Ipin na silẹ nwọn si ti nde si Enugu lati irọlẹ ana.

Oniwe irohin wa kan fi ye wa pe ọrọ abayọri eto ikania ti o jade laipẹyi ti Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria kọ ti nwọn ko gba ti nwọn si nju oko ọrọ si ara wọn lo fa lile ti Ijọba nle awọn Ibo.

### ỌRỌ B'ẸHIN YỌ

# IJỌBA FẸ DA AWOLỌWỌ SILẸ L'ỌGBA ẸWỌN !

EKO:— Gbogbo Ile lo palọlọ ti ẹnikẹni ko si sọrọ nigbati Ọgbẹni Mordi nsọ ninu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria pe ki Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria o ri wipe on lo aye rẹ lati da Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ ni ọgba ẹwọn ki o si pada wa ma a ṣe Olori awọn ọmọ Yoruba ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ọgbẹni Mordi ti iṣe ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N C.N.C.) ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ wipe bi o ba ṣe wipe Oloye Awolọwọ ba wa nile ni, iru aye ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wa loni kọ ni Ipinlẹ na yio wa.

O tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ wipe, lẹhin igbati Oloye Awolọwọ ko ti si nile ni ọja ko ti ta mọ, ko si owo nilu mọ, awọn si ri daju pe a fi ti Oloye na ba pada de ni gbogbo awọn nkan na yio to tun rọgbọ Bi bẹ kọ, gbogbo nkan ni yio tun ma a buru lọ siwaju si i ni.

Ọgbni Mordi tun ṣe alaye wipe gbogbo awọn ọjulowo ọmọ Yoruba, nile ati ni oko, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni nwọn nfẹ gẹgẹ bi Asiwaju wọn.

O wa ṣe alaye pe, ohun ti awọn enia ba nfẹ, on na lo yẹ ki a fun wọn.

O ni bi Oloye na ko ba tete pada de, sọdọ awọn enia rẹ, gbogbo nkan le tun ma a buru siwaju lọ si i ni dipo ti yio ma a rọlẹ.

Ọgbẹni Mordi ni, ti a ko ba ni fi ọmọri igba kan bọ ọkan ninu, ti a ko si ni ṣe ete lọṣọ, Oloye Awolọwọ lo to lo si yẹ lati maa ṣe Olori awọn ọmọ Yoruba.

O wa pe akiyesi gbogbo awọn nkan ti nṣẹlẹ lati igba ti Oloye na ko ti si nile si awọn ọmọ Ile Igbimọ O ni "Bi obinrin ko ba dan Ile ọkọ meji wo, koni mọ eyi ti o san ninu mejeji"

Lẹhinna ni o wa kesi Dokita Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria pe ki o lo aye ipo rẹ gẹgẹbi Olori Ijọba ki o si ri i wipe a da Oloye Awolọwọ silẹ ni ọgba ẹwọn ti o wa, bi o ba jẹ wipe nitootọ ni a ba nfẹ iṣọkan, ilọsiwaju ati ifẹ orilẹ-ede wa-Naijiria.

Ọgbẹni Mordi ṣe alaye wipe, aiko si nile Oloye Awolọwọ lo fa ọja ti ko ta mọ, aiko si Oloye Awolọwọ nile ni ko jẹki owo si nilu mọ.



Dokita Nnamidi Azikiwe
Olori Apapọ Ijọba Naijiriaa

Ọgbẹni Mordi ni laiko ti sọ gbogbo enia ti o ni ifẹ orilẹ-ede yi ni nwọnmọ gbogbo ohun ti on nwi yi, nwọn si le jẹri si ọrọ na pelu.

Wo oju ewe kẹfa

WA WO ERE

"Ọlaọrẹ Afọtẹjoye"

NI

Methodist Boys' High School, Eko

Ni 30/3/64, Ni agogo Meje Abọ

# ENITI NWON NDI KO TUN GBODO MA A DI OJU RIN

Lati Ọwọ D. A. ỌJẸNIYI (WISDOM) AWẸ

Siwaju ọrọ mi, mo juba Ọlọrun, mo si bẹru ọmọ enia, papa julọ awọn agbalagba awọn abu omi sẹnu fẹna, ina ko gbọdọ ku, bẹni omi ko gbọdọ jo danu (Iba o)

Mo tọrọ gafara lọwọ Olotu Irohin Imọlẹ lati le gba mi laye ninu iwe Irohin wọn akọmọlọgbọn. Ọlọrun ko ni ba ọpọlọ nyin jẹ, aiye ko si ni koju buburu dayin o. (Aṣẹ)

Enyin ọmọ Yoruba l'oko ati l'odo, mo ki nyin wipe ẹ ku otu, ẹo jire bi? Oduduwa ko ni jẹki iwa ọdalẹ ati aini otitọ ba orilẹ ede baba nla wa je o (Amin). Ohun ti mo nfẹ ba wa sọrọ le lori ni "KINI O NBA ORILẸ EDE YORUBA JẸ NI AKOKO YI?

Mo woye wipe awọn baba nla wa fi otitọ tẹ ilẹ Yoruba, nwọn si nfi otitọ ati ifẹ to jinlẹ ba ara wọn lo, o si dara fun wọn. Eyi lo fun wa ni anfani lati le ba ilẹ Yoruba ni ipo iwaju nigbati awa papa gbẹnju.

IWA ỌDALẸ

Ṣugbọn nigbati o bọ si ọwọ awọn to jẹ aṣiwaju lo de oni, nwọn fi eke ati iwa ọdalẹ kun eto iṣelu wọn, ifasẹhin si de ba orilẹ-ede Yoruba.

Owe awọn baba wa a ma sọ wipe "OJE, BI ABERE, BI ABERE NI ASE EKE, NIJOTI OBA TO OKO RO NI PANI". Iwa aisododo wa muki ari ibinu awọn oku ọrun wahala si de bawa, nitoripe ifẹ kosi mọ, iwa imọtara-ẹni-nikan lo ku.

Ohun to ya mi lẹnu julọ ni wipe, nigbati ilu ko toro, bawo ni ọba ilu ṣe le pagbo fun ijo?

Nigbati ede aiyede wa larin awọn ara ilu ti awọn ọba ati ijoye ko wa ọna lati ripe irẹpọ wa lọnakọna, ti nwọn tun wa nsare kiri wipe ẹgbe Oduduwa ko dara mọ, ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin kan lo tun dara, nibo ni nwọn wa ti ẹgbẹ Oduduwa fi di ibajẹ? Ki ṣe wipe gbogbo wọn ni nwọn fi idi ẹgbẹ Oduduwa mulẹ?

Bi ẹgbẹ Oduduwa ba to igbayi bajẹ, ka bi awọn Oba ati Ijoye, nitoripe nwọn ko mojuto ohun ti nwọn ni lati mojuto niyẹn.

Ede aiyede tiwa nipa iṣelu, ẹ tun nda ede aiyede miran silẹ nipa ẹgbẹ ọmọ ibilẹ Yoruba, o yẹki awọn Baba ati iya wa ronu wo, gẹgẹbi orin OGUNDE.

Nigbati wahala ti Awolọwọ delẹ inu ọpọlọpọ awọn Yoruba ti ori wọn ko pe ndun, ṣugbọn loni nkọ, o ti han si gbogbo wa wipe, bi ori ba kuro lọrun ara bajẹ.

Nigbati Awolọwọ wa ninu Ijọba eṣe ti awọn Ọba ati Ijoye kofi damọran ati da ẹgbẹ ỌLỌFIN silẹ?



OLOYE AWOLỌWỌ

Tabi nwọn sẹse lala ri nisisiyi wipe ỌLỌFIN i ada pe oriko ODUDUWA nisisiyi ni?"

IFẸ IK ORIRA

Ko si ohun ti emi fẹki o ye wa nibẹ ju wipe ẹgbẹ Ọlọfin ko jade pẹlu ẹmi ilọsiwaju fun ọmọ Yoruba bi ko se fun ifẹ ikorira, ati ijẹkujẹ awọn olori wa, ti nwọn ti rope nigbati awon tilẹ sin Awolọwọ de ẹwọn tan, bi awọn ko ba pa eto rẹ re, awọn le ma ri nkan jẹ mọ

Ṣugbọn ki ẹ maṣe gbagbe wipe ọro Ọlọrun so wipe "TEMI NI ẸSA, — EMI O SI GBẸSAN"

Ki ba ṣe Ọba ki ba ṣe Ijoye, Olowo, tabi Ologun ko si ẹniti o le ri ogun esu se ki ẹ jeki o ye gbogbo wa wipe "EKE ṢIṢE KO WIPE KI A MA GBE ILE AIYE PE, ILẸ DIDA KO PE KI ENIA MA GBILẸ BIỌGẸDẸ, ỌJỌ ATISUN LẸBỌ

Imọran ti emi fẹ fun wa ni wipe awa ti a ba jẹ ọmọ ọkọ ejẹki afi han ninu iṣe ati iwa wa wipe "ỌMỌ ỌKỌ NI OGUN ỌMỌ ALE" pẹlu emi otitọ ati ifẹ, ki a si mọ wipe Ọlọrun kosi lẹhin alabosi.

Ki ẹ maṣe gbagbe orin awọn Musulumi to so wipe "LOTITỌ ALABOSI LE MA A LOWO LOTITỌ ALABOSI LE MA BIMỌ. ṢUGBỌN ATUBỌTAN ALABOSI KO NI DARA."

Ki ẹmọ wipe gbogbo owo ti o fọ awọn kan loju inu ati ti ode koje nkan kan loju Ọlọrun, nitoripe bi nwọn baku, nwọn ko le mu kọbọ kan lọ sọrun.

Lotitọ olowo, ọlọla oni po ọba ati ijoye le ṣe pataki loju awa eda nwọn ko to ori igbalẹ ọwọ lọdọ, Ọlọrun

E jẹki gbogbo wa pajuba silẹ de iṣu amodun, ka jẹ oruko todun silẹ de ọmọ ẹni. ka maṣe jẹki Iwa wobia ati ọdalẹ sọwa di ọta Ọlọrun, nitoripe awọn kan ti ṣe bẹ ni odoogun, Yemaja logbe wọn lọ.

ỌWỌ ESAU

Ko si igbati iru iwa aiṣotitọ ati aiṣododo bayi le wọn larin Yoruba, nitoripe orilẹ ede to ba fẹran owo ju Ọlọrun lọ. ero ẹhin ni yio da botiwu ko lagbari to.

Larin Yoruba, ọpọlọpọ lọ jẹ wipe nipa ifẹ owo Hausa lo daṣẹ wọn, awọn mirati wa ti ojẹ wipe Ibo lo daṣẹ wọn, bawo ni aṣe le ṣe ebolo tiko ni irun igbẹ, bawo ni aṣe le ṣe ọmọ aṣẹgita tiko ni fi huwa epo igi?

Nigbati Hausa, Ibo, tabi kurumo daṣẹ enia, to dagba tan ti ẹ wa sope on loyẹ ni aṣiwaju nilẹ Yoruba, ko si ọna ti o le gba Yoruba de ọkan, nitoripe "ARA NI ARA ESAU ṢUGBỌN OHUN NI OHUN JAKỌBU".

Mo fẹ ki gbogbo ẹnyin agbalagba, ati oniwe wa, ronu jinlẹ lori awọn ọrọ ni wọnyi

Ki e jẹki a mu ọrọ ti oṣelu kuro, ki otitọ ọrọ le raye jade sira wa, nitoripe ki ẹgbẹ oṣelu to de ni ilẹ Yoruba tiwa, ko si ni to ki a sin ẸDA ju ẸLẸDA lọ nipa ifẹ afẹju ti ẹgbẹ oṣelu.

Ki ẹpe daradara, ki ẹro daradara, bi ko bati ho ẹ maṣe fi ogun si, nitoripe bi a ba fi ogun si, omi tiko ba ti ho, o ni lati tiri ni.



DOKITA AKINỌLA MAJA

Ọran Yoruba ti wa di igbati birikoto ti imọran de mẹlẹ, Ọka nbẹ nibẹ tole binu jẹ, akekere nbẹ tole tani.

Ẹ jẹki a fi Obara mu Ogbetura, ki ati idi mu igi gun ko le ye gbogbo wa,

Ọlọrun Ọba ati Oduduwa, pẹlu awọn alaiye yio ba wa tun ilu Yoruba ṣe. Yio yipada fun owo, fun ọmọ, alafia ati irọra (AṢẸ).


AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

Free illustrated catalogue on demand

Réf. N° 55. PHOTO

A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non magnetic, unbreakable mainspring. ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved.



PRICE £ 5.

WINDSOR

19, Avenue de Lérins — Cannes. France

# IWE SI OLOTU

## Imam Agba, O D'owo Nyin O

Ile aiye ki se ibiti ao gbe titi lailai. Iku yio pa wa, bi a fe bi a ko. Gbogbo wa ni a je gbese iku, e jeki a ma a se eto nigba gbogbo. E je ki a be Olorun fun iranwo, ki O le ma a to wa sona.

E jeki a mo pe, Olorun ko fe rigimo" Olorun ko fe tembelekun tabi iwa yiyoleda tabi iwa fiforimookun ba enikeji eni je. Olorun ko si fe ote. Ote nte enia ni Ire po ninu isokan ati ife.

Pelu iteriba ni mo fi be Hadji Imam Agba Liadi Ibrahim, omoluwabi, ati awon Lemomu Ratibi lati ba awon Jaoma won soro aso ye pelu su'ru mpa ote. Ote nda ct ire ru ni, ki i mu nkan toro Egbe ni fun olote, alamori re yio daru.

Lenuleloyi ni okan ninu awon olote ayoleda ti ko ronu jinle, ki o si sun ki o wo oye, je ki nwon da Lemomu Mosalasi olokiki kan l'Eko duro fun igba die lai gbo t'enu re rara, lori ese kan ti nwon ka si i lorun, ati lai gba ase Lemomu Agba ti o peye.

Afojudi yi ma a po o. Howu!

Emi ni,
ALHADJI AWAIYEWASERE
Eko.

waju ile wa. Ti a ba wa ninu ede aiyede, ko si ohun rere kan ti a a le se sugbon ti a ba wa ninu irepo gbogbo nkan ti a ba nfe, ni yio ma a se deede fun'wa.

Nitorina e jeki a lo pa ote ti, ki a si gbe ewu ife wo, ki a pari re, oku ojo meje kuro n alejo sare o

Alubata ki idarin, o to gee

Emi ni
R. AJISAFE OLADIPO
Ijomu—Oro

## A dupe O

Olotu, jowo gba mi laye lati dupe lowo awon Alase Ijoba Ibile Idofian fun ibudo moto titun ti nwon sese ko si ilu wa. A dupe, e se e, e ku ise o. Oko Oba ko ni sa nyin lese o.

Inu wa yio dun lopolopo ti e ba le fi panu ko awon ile ti o wa nibe dipo koriko ti nwon fi ko ile na nisisiyi Ile koriko na lo bu gbo gbo ise nyin ku.

A lero wipe eo tete fi panu ko ile na ki awon ara ilu miran mase ma a pegan ilu wa.

Olotu, mo dupe aye ti e gbami, Imole nyin ko ni di okunkun o

Emi ni
M A.A. IDOFIANLOMOWA
Idofihan-Ilorin

## E mojuto Awon Omo Ile-Iwe

Bi Olorun ba nso wa, o y: ki ama so ara wa. Yio dara lo polopo ti awon Alase Ijoba Ibile Eko ba le maa mojuto awon omo Ile-Iwe ti nwon ma a fo mo boosi ni ojoojumo.

Gbogbo abiyamo ti o ba nri awon omo wonyi bi nwon ti se ma a nfo mo boosi oju oluware yio pa kannakanna, Ooyi o si ko oluware pelu.

Awon omo na atun ma fo sokale nigbati boosi ko ti duro, Orome-adie ko mo awodi iya re ni o mo asa

Nitorina, a be awon Alase Ijoba ki nwon o maa kilo fun awon kondokito ki nwon mase maa gba awon omo l'aye lati maa fo mo boosi mo Emi ko ni aro o

Emi ni,
ADESEGUN STEHPEN
Ebute-Metta

## Imoran fun awon Omo Ijomu-Oro

Jowo gba mi laye lati kesi gbogbo awon omo ilu Ijomu lori oro Oye ti o da ote sile ninu ilu wa Bi enia meji ba nja, enikan ni o gbodo segun Nigbati awon enia meji ti beresi ja si oye ti o si ti bo si enikan lowo ija ti tan

Nitorina, e jeki gbogbo wa lo pa ote ti si egbe kan, ki e si jeki a ma a wa ire ati anfani ilosi

## Sanmora nfe Omi Ero

Jowo gba mi laye lati kesi awon alase Ijoba Ibile Sanmora ati paapa julo Ijoba Ipinle Ariwa pe ki nwon jowo ki nwon fun ilu wa ni Omi ero.

Ilu Sanmora ko kere larin ilu ti o wa ni Ipinle Ariwa papa julo ni agbegbe Ilorin Okan pataki ni ilu oa ise. Beni a ki i si fi owo-ori jafara ni odoodun. gbogbo wa ni a nda a.

Inu wa yio si tun dun bi Ijoba rere na ba le tun fun wa ni titi Oloda laipe yi

Emi ni
EZEKIEL ATOYEBI
Sanmora Ilorin


## Akiyesi Pataki

A nfe Asoju ni awon ilu wonyi, Otta Abeokuta, Ibadan, Iludun, Olodo, Agbowa,-Iko si Ikorodu, Oyo, Awe, Ilesha, Ede, Ikirun, Iwo Shaki Iseyin, Tede, Oke Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajasse-Ipo, Iffo Abalabi, Idogo.

Akowe si
Circulation Manager.
Gbamgbose Street,
Lagos.


# Igbimo Atunto Egbe Imole Aiye

GEGEBI a ti fi ase fun mi lati odo awon Igbimo atunto egbe Imole Aiye pe, awon ti tu egbe Imole Aiye tele ka, a si ti tun da omiran sile nitorina ti o ba ri pe o fe je okan ninu omo egbe t tun yi ki o kowe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ojo kokanla osu kerin (11/4/64) ni dede agogo meta osan.

Egbe yi yato si ti atehinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awon ere ti egbe titun na yio ma se.

1. Lati maa ko awon odo ile yi ni ona bi a ti nko irohin, itan, oro sinu iwe Irohin lati odo awon Ojogbon oniwe Irohin
2. Ere bi Boolu alafese gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo. Ise. Draft Ludo Picnic ati opolopo awon nkan miran ti eo ma a gbo ni ipade.

Nitorina ti o ba fe tun je okan ninu awon omo egbe titun yi, ki o wa si ipade ni ojo 11/4/64 ni nomba 16, Bamgbose St., Lagos, Ao si tun yan awon alase egbe titun.

Eyi ni oruko awon Igbimo atunto egbe Imole:—

1. J. Ola. Okunlola
2. Latifu Babalola
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awelenje
5. Timothy Akins

E jowo, e tete de ipade o.


BERE OJULOWO EGBOGI:—

## Congreve's Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awon obinrin ti o ba ni iyonu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekookan ehin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ejedudu lara tabi aikoto eje lara Inu gbigbona nigbakugba

Igba — aiya riru omu riro, didun are atinu wa t oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ese ara sison, efori tabi pelu iba ati otutu Egbogi yi dara pupo julo fun itoju gbogbo O b i n r i n gegebi Ajo fun ilera ati orisirisi amodi miran ti o ma nyo won lenu ni inu nigbakugba pelu.

(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI ATI JO TI WON NPE NI:-

## mmoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awon Orisirisi robiroki egbogi ti won uko wa nisisiyi to de awon agbalagba aiye atijo mo daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu iko ita, orere lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyo enia lenu fyala Omode tabi agbalagba ni yio se iwosan re bi danga ni bi oba ti ta die sinu omi ti o loworo ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itoju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfo apo-ila-ito tabi se iwosan iyonu apo-ile-ito egbogi oju didun tabi ti owa-ofun didun, ati orisirisi omiran pelu won mbe ni sobu awon :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone: Nigeria, (Oja Ita Faji)

# Ọgbẹni Mathews Ni Aṣoju Ijọba Amerika Ni Naijiria

WASHINGTON:— Oloriḡilẹ Amẹrika Ọlọla Johnson ti yan Ọgbẹni Elbert C. Mathews asoju igbimọ Ijọba Ile Amẹrika ni Naijiria. Ọgbẹni Mathews ni yio rọ pọ ọgbẹni Joseph Palme Keji fi ilẹ Naijiria silẹ lati gba ipo titun ni pari ọdun ti o kọja yi.

Irohin fi ye wa wipe Ọgbẹni Mathews ti jẹ aṣoju fun ilẹ Amẹrika ni Liberia fun ọdun meji ṣẹhin, ki o to pada si Amẹrika ti o si ṣiṣẹ ni ile iṣẹ ti o wa fun ilọsiwaju ilẹ Afrika fun oṣu mẹfa, ki o to wa di pe nwọn yan an si ipo titun yi.

Ninu oṣu kẹjọ ọdun 1963 ni agbọ pe o bọ si ipo adari ile iṣẹ to nmu oju to alafia ilẹ Afrika ati pe awọn iṣẹ rẹ ni lati mojuto awọn ohun ti o le wulo fun ilẹ na, pẹlu irẹpọ larin orilẹ-ede wa.

Agbọ wipe Ọgbẹni Mathews ti bẹrẹ iṣẹ rẹ gẹgẹbi ẹniti o mọ nipa ilẹ Afrika lati nkan bi ọdun 1935.

A si tun gbọ wipe Ọgbẹni Mathews ti ṣiṣẹ ni awọn ilu wọnyi, India, Turkey Norway, Australia ati Afighanistan pẹlu iṣẹ rẹ ni Liberia.

Ọgbẹni Mathews gba oye ẹkọ rẹ lati ile ẹkọ giga Unifasiti Califonia ati ti ile ẹkọ giga julọ ti Unifasiti Pennsylvania.

Ọgbẹni Mathews yio de si Naijiria laipẹ yi lati wa bẹ rẹ iṣẹ rẹ

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan.22–Feb.20) Irin ajo ti iwọ ko ro tẹlẹ le ṣẹlẹ si ọ loni, ọdara ki o lo sinmi lọwọ awuroyi maṣejade lọ sibikan titi ilẹ yio fi su.

PISCES (Feb. 21 – Mar. 20) Maṣe fi ọkan si ironu ohun kan ti o sọ nu lọwọ rẹ. Ọrọ ti iwọ pẹlu obinrin kan jijọ sọ yio daru

ARIES (Mar. 21 – April 20) Ewu mbẹ fun ọ loni lati ọdọ obinrin kan ti yio fi nkan paju wa ba ọ nitori ki ẹ ba le jijọ sere pọ

TAURUS (April 21 – May 20) Ṣọra loni ki agbana ma ba wọ inu owo ti o ni lọwọ, maṣe na inakuna fun ifẹ obinrin

GEMINI (May 21 – June 21) pọ enia yio ba ọ ṣọ rẹ loni, ṣugbọn maṣe tete gbe ara le wọn ki nwọn ma ba da ọ.

CANCER (June 22 – July 23) Pupọ enia ni yio ṣe atako si ohun kan ti o fẹ se ninu ile nyin ati lode tun ọrọ na ro daradara ki o to dawọle.

LEO (July 24 – Aug. 22) Ko nṣe ohun ti o wa ni ifẹ rẹ lati ma kẹgbẹ, eyi dara bẹ, ṣugbọn maṣe huwa ti fo lodi si eyi.

NIRGO (Aug. 23–Sept. 23) Gbogbo iṣẹ ti o ba dawọle loni ire ni yio gbẹhin rẹ ojọrọ ọjọ oni yio dara fun o pupọ

LIBRA (Sept. 24 Oct. 23) Ọjọ oni ṣoro jọjọ fun o ṣugbọn bi o ti wu ki o ri iwọ ni yio bori gbogbo ọta rẹ maṣe binu

SCORPIO (Oct. 24–Nov. 22) Ṣọra loni ki o maṣe ore ti ko ni gọmi o maṣe jẹki nwọn ti ọ de ipo ti iwọ yio fi ya enia lowo loni eso di owo rẹ nitori awọn onijibiti

SAGITTARIUS (Nov. 23 Dec. 22) Bi o ba nawo fun awọn ara ileṣẹ yio ṣe o ni anfani jọjọ ki osi ri okodoro nkan daju ki o to tẹṣẹ bo iyẹn lọ dara fun ọ

CAPRICORN (Dec. 23– Jan 21) Iwe kan ti o ti nreti wa lana o mbọ wa tẹ ọ lọwọ Awọn Obinrin yio ma ṣe rọkẹrọkẹ si ọ iṣọra ni ẹbọ.


# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"

MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA, KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogboẹda patapata" Amin.

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati wọn ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6. £3 fun dosinu*

MANAGER

N2/99 SHITTU STREET

Ibadan



# Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọ laílai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

## "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bere si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store

8, Palm Church Street Lagos.

Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

*FUN*

**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

**'gbe yawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16 Bamgbose Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985. Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

OWO *POKU* NI A *SI NBGA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Danwa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# Ẹsan De Si Orilẹ Aiye

Lati Ọwọ WOLI KOGBEREGBE, MUSHIN.

Gẹgẹbi mo ti nsọ nipa awọn ohun ti Oluwa fi kan mi wipe yio maa ṣẹlẹ si awọn Ọmọ araiye ninu Ọdun ti a wa ninu rẹ yi ati Ọdun ti nbọ, on na ni mo ti tun maa balọ ni Owurọ yi fun anfani gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ.

Ẹ ṣọra ki ẹ ma ṣe fi ẹmi yin wa owo, ija kan yio ṣẹlẹ lori awọn oṣiṣẹ, ọkọ ofurufu kan yio ja ninu oṣu ọdun titu, ẹ mura si adura nitori eyi o.

Ẹ gbadura fun awọn Kafinta, nitori ewu wa lori wọn, ẹ gb dura nitori iku Ẹlem kan lati ẹri ọpẹ, ọpọ ile ni yio wo lulẹ ninu ọdun 1964.

Ẹ mura si adura nitori eyi o Oluwa ko ni fi gb - gbo wa le iku aiye lọwọ o.

Ẹ gba adura nitori igi tutu ti yio ma di gbigbẹ ni ọjọ iwaju, eṣu de yio tun wa ie gbogbo nkan tuntun ti awọn agbe ba gbin.

Ẹ mura si adura nitori ekun lati ilu oyinbo wa. Oluwa yio gbe wa leke iṣoro wọnyi o.

Ẹṣẹ ti pọju ire lọ lode aiye l-a ! awọn ajẹ fẹ fi epo gbigba, gbigbona ṣe jamba lode ninu ọdun yi ki gbogbo enia ṣọra nidi epo gbigba, ẹ mura si adura o.

Ẹ lọwọ, ẹ ṣọra lati ma finu han enia pe ọpọ enia ni yio ma fi itara ba ohun rere jẹ, idarudapọ kan yio ṣẹlẹ ni ilu Eko yio si ṣẹlẹ ni ilu Ibadan.

Olori ẹlẹṣẹ kan yin ku okiki yio si kan, ẹ gbadura nitori eyi o.

Ẹ ṣọra lati ma jẹ obi, nitori pe awọn ajẹ fẹ fi majele si ara obi na, ẹ mura si adura nitori Bọsi kan yio jamu yio si pa ọpọ enia lara

Ẹ fi adura ran awọn Ọmọ Ile-Iwe giga lọwọ, ọpọ ninu wọn ni ko ni ṣe dada ninu iwe rẹ yio si lọ fi binu ja sinu omi. Oluwa yio ko wọn yọ o, Amin o Jesu

Anu ṣe mi wipe ọkunrin kan yio ti ilu oyinbo de ninu ọdun yi awọn enia rẹ yio si ti gbe ko to silẹ fun

Awọn ọmọ ile iwe yio ku pupọ nitori oyun bibajẹ, nitorina kilọ fun ọmọ rẹ, ko ma se ba oyun jẹ o

Wahala vi pọ ju iṣẹ lọ ninu ọdun to mbọ yi o Ọja ki yio ta mọ rara o.

Ile epo kan yio jona ni ọna Apapa ninu ọdun yi

Anu ṣe mi wipe ẹnyin yio gbọ iro iku ọlọla kan, okiki yio si kan, gbogbo aiye ni yio mi titi

Ẹ mura ki iku ọlọla na ma ba da ogun silẹ lori ilẹ aiye bẹ si ni iku adajọ yio pọ, ti adajọ na ko ni ro tẹlẹ.

Awọn ọlọla kan yio ṣe ipade kan ija yio si ṣẹlẹ nibẹ, oku mẹtani yio ku ni bi anejo yi. Awọn angẹli kan yio sọ kalẹ sori ile aiye.

Awọn angẹli yi o si ma wọ inu ile kiri bi oludanwo, ki enia kan maṣe pẹlu alejo kan ninu erun ọdun yi, ẹ mura si Adura nitori iṣẹ ni a ti yio ma ṣọ ni adugbo ti a korọ tẹlẹ

## ANGẸLI OLUWA

Ọyẹ to nbọ ninu ọdun 1964 yi ko fa ohun rere dani o ẹ mura si adura Oluwa fẹsan ẹsan fun aiye ẹ gbadura fun awọn to npa ẹja loju o mi oriṣa to wa loju omi ti wipe enia ni on fẹ gba on ko gba ẹran.

Awọn angẹli Oluwa si bi oriṣa yi lere wipe kini ohun to de ti iwọ ko fi jẹ ẹran, ti o fi jẹ pe, enia ni o fẹ ẹjẹ?

O ri ṣ a inu odo na si da awọn Angẹli Oluwa lohun wipe, ki iṣe ẹjọ mi, awọn enia na lo nfi enia bọ odo, ti nwọn si nta ẹjẹ enia silẹ fun wa lai bere lọwọ wa o si ti dun mọ wa lẹnu, awa ko le jẹ ẹran miran mọ, bikoṣe ẹran enia.

On lo fa ti a fẹ fi mu ninu awọn enia to npa ẹja fun lilo tiwa, awọn Angẹli nako si le da oriṣa na lẹbi, nitoripe a fọwọ fa enia ni.

## ALAKOBA

Nitorina mo fẹ ki ẹ lọmọ wipe nitori ọmọ ọlọmọ ti nwọn gbe bọ igi bọ odo ti nwọn si tun nfi wọn ṣe owo on ni yio fa iku omi ti agbara ẹjẹ yio fi ma wọ ka ilu.

Oluwa fẹ gbẹja gbogbo awọn ọmọ ti nwọn ti lọ . iṣe owo, Oluwa ni on fẹ gbẹsan lara awọn enia to lọ fi ọmọ ọlọmọ ṣe owo. Ha! ibinu Oluwa de si aiye, ko si enia ti ibinu na koni kọlu o nitorina gbogbo ẹnyin onigba gbọ ati onimale, ẹ lọ tewọ adura, Oluwa yio gbe wa le ke awọn alakoba.

Ẹ gbadura ninu ọdun December yi o, ija yio pọ ninu aisun ọdun yi o, iku yio si pọ ninu aisun ọdun yi.

---

# Gbanjo! Gbanjo! Gbanjo!!

Eyi ni lati kede fun gbogbo awọn ONIBA... wa jakejado agbaiye pe ao beresi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gegebi iṣe wa lọdọọdun, Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tetebere GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

OJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 2...th MAC -30th APR

Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/- di 22/6d

Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu ṣiṣe 21/- di 18/-

Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalm Isẹgun Ajẹ 4/6d di 3/-

Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d

Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6 di 2/-

Turari Isẹgun Ajẹ 10/6 di 8/-

Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-

Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d

Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-

Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-



AKIYESI:— Enikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba 'TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa wo.

Shoyinka
N2/99 Shittu Street,
Ibadan

---

# Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

---


AH ! REMEMBER THAT

# The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid-Ul-Kabir Dance

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Officess Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 566 SATURDAY MARCH 28, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọle ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi yọ gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# ENITI O ṢA IYAWO RẸ L'ADA WẸWỌN ỌDUN MẸRINLA

EKO:- ti ẹo ba gbagbe ọkunrin gende kan ti o fi ada sa Iyawo rẹ larin ọdun 1962 ti awọn ọlọpa le mu larin ọja Sandgrouse orukọ rẹ ni Raheal Ọlabanji.

Lẹhin igbati ile ẹjọ ti da ẹwọn ọdun mẹrinla fun Ọlabanji fun ẹsun pe o fẹ pa Iyawo Mopesọla Ayinkẹ ati pe o tun da ọgbẹ si lara ti o si tun fi ẹnu Iyawo rẹ wu ewu ni oba tun pe ẹjọ ko tẹmi lọrun eyiti nwon ṣe larin ọsẹ ti o kọja yi

Nigbati nwọn gbọ ẹjọ ko tẹmilọrun yi, awọn adajọ agba mẹta ti ilu Eko, ọlọla L. Brett tiṣe adele agba fun adajọ ap pọ Ijọba ilẹ Naijiria, ati ọlọla J. I. E., Taylor ati ọlọla Vahe Bairamian fi han pe awọn kọ ri si idi ti Ọlatunji fi so pe ẹjọ ti nwọn da fun on. kọtẹ on lọrun.

Onirohin wa ran wa leti wipe, Ọdaran yi, Olabanji jẹ dẹrẹba moto ti ngbe Okeado ni Ibadan

Asi tun gbọ pe ni igbati Ọlabanji ti ibi iṣẹ rẹ de ti ko ba Iyawo rẹ Ayinkẹ nile ti wọn si yọ sọ fun pe Iyawo rẹ ti sa ba ọkunrin miran lọ ni o ba gbiyanju wọkọ lọsi ilu awọn Iyawo rẹ ni Oshogbo.

Nigbati kori ni o ba ti ibẹ lọ si ilu Ondo bi Ọlabanji ti pada de si Ibadan ni o ba gbọ wipe ẹnikan ti lọ jawe ikọsilẹ fun Iyawo on.

Osi tun gbọ wipe nilu Eko ni nwọn ngbe pẹlu Iya Iyawo rẹ. were ni Ọlabanji ba gba ti Eko wa ti o lọ si ile ti Iyawo rẹ wa o ki Iya Iyawo rẹ o fi ọrọ na han pe on ko mọ ohun ti o nṣe Iyawo on ti ofi sa a fi on silẹ gbigbọ ti on ma gbọ nwọn tun lọ fun on ni iwe ikọsilẹ.

Bi o ti sọrọ yi lọwọ ni Iyawo rẹ ba wọle de ni Iya Iyawo rẹ ba sọ fun Iyawo wipe ki . ma tẹle ọkọ rẹ lọ.

Ṣugbọn nigbati ko ṣeṣe ni Iya Iyawo ba sọ fun Ọlabanji pe ki oma lọ si Ibadan.

Bi Ọlabanji ti reti fun ọjọ mẹta ti ko ri iyawo rẹ ni o ba tun ta mọra lo ba tun pada si Eko.

Ọlabanji nhan ile ẹjọ wipe bi on ti wọ inu ile ana on ti nwọn fi oju kan on ni nwọn ba kegbe ole le on lori ti nwọn si lu on ni alu domi si lẹnu.

Ọlabanji ni bi atẹgun ti fẹ si on ti on si taji ni o tun gbe orisoke ti on fi oju ri ada kan ni ẹgbẹ ile ni on ba fa yọ ti on si fi ṣa awọn ti nwọn lu on.

O ni on ko ni ero lati fi ada na pa ẹnikankan lara ṣugbọn nigbati nwọn ti fi iya jẹ on lo jẹ ki on ṣe bẹ.

Ninu ọrọ aya rẹ Ayinkẹ fihan ile ẹjọ wipe Ọlabanji na gba on fẹ lọdọ okunrin miran ni ti o si san owo ponun mẹdogun (15) ni ile ẹjọ Ibilẹ ti Ibadan.

O tun fi han wipe nigbakugba ti awọn bati nṣe awo larin ara awọn nṣe ni ọkọ on ma fi ada ati ọbẹ dẹruba on.

Ayinkẹ tun sọ wipe lati igbati on si ti kọ Ọlabanjọ silẹ on ti da ponun mẹdogun (£15) rẹ pada fun.

O ni ni ọjọ ti on ma foju kan Ọla-banji ni o ba fa ada yo labẹ agbada rẹ ti osi fi sa on yana yana.

Ninu Idajọ wọn, awọn adajọ fi han wipe awọn ko ri idi ti Ọlabanji fi le sa a aya rẹ ni ada.

Nitori idi eyi, nwọn ni ki o lọ ṣe ẹwọn ọdun mẹrinla na pẹlu Iṣẹ aṣekara.

## Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe gbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ iṣẹkuo.

OLOTU

Lati Oju Ewe Kinni

Ni ipari ọrọ rẹ, Ọgbẹni Mordi ni ko si ẹniti aye ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wa loni, ko nkọ ni ominu, bi gbogbo ọmọ Ile Igbimọ Asofin ba si ri wipe aye ti Ipinlẹ na wa ko dara, awọn enia Ipinlẹ na ko fẹ ohun ti nlọ nibẹ bayi, o yẹ ki a ṣe ohun ti nwọn ba nfẹ fun wọn

Ohun ti awọn enia na nfẹ ni pe ki Oloye Awolọwọ o pada wale, ki itura ifọkan balẹ, aiko fi ipa mu ara ẹni ṣe ohun ti ẹnikan ko fẹ.

Ki Ọgbẹni Mardi to pari ọrọ rẹ o ni ki iṣe ẹgbẹ Oṣelu titun ti Oloye Akintọla da silẹ ni awọn enia Ipinlẹ na nfẹ ki alafia ati ifaya balẹ o to lede bi ko ṣe pe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Niipari o ni Oloye Awolọwọ ni gbogbo ojulowo ọmọ Yoruba nfẹ ni Ipinlẹ na lati maa wase aṣiwaju wọn ti a ba nfẹ ki Ipinlẹ na o fẹraro pelu ifaiyabalẹ

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe Apapọ Ijọba nro ọrọ na lọwọ bayi Awọn oniwe si ti lọ jiṣẹ fun ọlọla Nnambi Azikwe.

Bi nwon ba tun sọrọ na si eo tun ma a gbọ o.

Agbọrọsọ sọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ kan fi ye Oniwe irohin wa lẹhin ti nwọn pari ipade wipe.

Ina njọ lọfun amukoko, ohun ti nṣẹlẹ si ẹgbẹ Alakukọ nisisiyi le ju ohun ti o ṣẹlẹ si ẹgbẹ Afẹnifẹre lọ, okun fẹ mu ẹran"

Nitorina, awọn nfẹ ri Oloye Awolọwọ, ki Ijọba o si tete fi silẹ laipẹ yi.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (28/3/64)